**ISAIAH 62 AWE FUN GBOGBO AGBAYE**

**ISAIAH 62 (AISAYA ORI KEJI-LEL'OGOTA) AWE ATI ADURA OLOJO MOKANLELOGUN FUN GBOGBO AGBAYE**

Darapo mo awon onigbagbo ti o ju milionu kan lo ti yoo se alabapin ninu adura fun Israeli fun o kere ju, wakati kan ni ojo kan bere lati ojo keje si ojo keji-dinlogbon osu Ikarun (May 7-28) fun itesiwaju imuse awon ileri Olorun ati eto Re fun Jerusalemu ati Israeli. Lara awon eniyan yi yoo da gbadura nigbati awon miran yoo korajo ni meji tabi jubelo lati jo gbadura yi. (Matt. 18:20) – Yala lori ero ayelujara tabi foonu, tabi ki won korajo ninu ile won, tabi ni ibi ise won, tabi ninu ile ijosin won.

Ifowosopo egbeegberun awon ise iranse, ijo Olorun pelu awon iranse Olorun bi Lou Engle, Jason-Hubbard, Mike Bickle npe awon omo Olorun toto milionu kan lati kopa ninu apejo mimo agbaye kan ti yoo bere lati ojo keje si ojo keji-dinlogbon osu Ikarun (May 7-28) lati gbawe ni awon ona orisirisi ati lati gbadura lori ipinnu Oluwa fun Israeli ati lati bere lowo Oluwa ki o le gbe awon alore toto milionu lona ogorun dide lati ma gbadura fun israeli ni ibamu pelu awon ileri Re ninu iwe woli Isaiah 62:6 pe ki Oluwa ki o lo ase Re bi Oba Alase lati 'yan' tabi 'samisi' ara awon alore ti yoo ma ran Oluwa leti nipa awon ileri Re fun Israeli.

***<u>Emi ti fi</u> awon alore sori odi re iwo Jerusalemu, ti ki yio pa enu won mo <u>losan ati loru titilai</u> enyin tin se iranti Oluwa <u>e</u> mase dake. E mase fun U ni isimi, <u>titi</u> yio fifi idi Jerusalemu mule, ti yio se e ni iyin li aiye. (ni igba bibo Jesu). Isaiah 62:6-7***

Ojo mewa akoko lehin ti ikede yi jade ni ojo keje osu iketa (March 7) o le ni iwon egbeerun lona ogorun meta awon eniyan ti won pinnu lati kopa ni oniruuru ona. Ti o ba ma fi di ojo keje osu Ikarun, yio ti le ni milionu kan eniyan ti yoo kopa ninu awe olojo mokanlelogun yi ni awon oniruuru ona (Awon kan yoo gba awe biribiri pelu omi, awon miran yoo gba awe won pelu eso ati ewebe, tabi ki won jeun leekan lojumo, nigbati awon miran yoo gba awe won nipa didi oju won si ero ayelujara, telifison ati radio dipo ounje.

Ni iyara adura ti **IHOPKC,** won ti pinnu lati gbadura ati lati josin fun Oluwa laidake l'osan ati l'oru fun Israeli ni gbogbo ose meta yi bere lati ojo keje si ojo keji-dinlogbon osu Ikarun.
O le ni ogorun meta ninu awon osise **IHOPKC** ti o ti pinnu lati wa ninu iyara adura fun wakati mefa si wakati mejila lojoojumo fun gbogbo ojo mokanlelogun yi.

Mo dupe fun idahun won lati fi opolopo awon ojuse deede won sile lati se eyi! Iyara adura **IHOPKC** je okan lara awon ibi to se alabapin ninu adura yi. Fun alaye die sii lori bi ile-ijosin tabi ise-iranse re se le kopa bi eyi wo (isaiah62fast.com) tabi Isaiah62fast facebook page ([https://rb.gy/8orcjp](https://rb.gy/8orcjp)).

Ni Isaiah62fast.com ni a ti se afihan awon ile-ijosin, awon ile-ise iranse, awon eko Bibeli, awon egbe odo, ati bebelo ti o fe lati je ibi Pataki ti yoo ma pese awon ohun ti a nilo, ibara-eni-soro deede, ati bebelo ni riru awon eniyan soke fun ojo mokanlelogun yi. Ti o ba fe ki oruko ijo tabi ise iranse re wa lori oju ewe Isaiah62fast.com te ona asopo yi fun alaye die si.

Isaiah62fast.com ko salaye nipa eto Olorun fun igba ikehin sugbon o npe gbogbo onigbagbo ni ibi gbogbo lati kopa ninu adura yi.

**Kini idi milionu lona ogorun?**
Ni opolopo odun seyin, ni Oluwa ti so asotele nipa ogorun milionu eniyan ti yoo ma gbadura ati bebe ni oniruuru ona fun Israeli.
Eric Watt, Jason Hubbard (IPC) ati awon omo egbe won ti sabewo si IHOPKC ni opolopo awon akoko ni awon odun die sehin.
Won nse asoju ati ibasoro nigbagbogbo pelu awon oludari tin se abojuto awon ile adura ti o le ni egberun marun ti apapo awon to ngbadura si to aadoje milionu awon onigbagbo (o koko soro fun mi lati gbagbo). Ninu ibewo won ni osu ikejila odun to koja (Dec. 2022) won salaye pe awon adari ile adura to le ni egberun marun yii pelu awon adoje milionu alore ti o sopo mo won yoo duro papo lati gbadura fun agbegbe kanna lori ile aye ni emerin otooto ninu odun ti a wa yi (2023) ninu ise-iranse fun gbogbo agbaye ti a pe oruko re ni <u>110cities.com</u>. O je ohun to jomi loju latiri pe eyi ni igba akoko ninu itan eniyan ti a o ri awon onigbagbo ti o le ni ogorun milionu lati gbadura fun agbegbe kanna ni ojo kanna ni emerin otooto lodun kanna (John 17:21-23)

Awon eniyan milionu lona ogorun yi gbadura fun orile-ede China ni ojo kejilelogun osu Ikinin odun yi (January 22, 2023). Won yoo gbadura fun awon orile-ede ti o wa ni Aringbungbun-Ila oorun aye ni ojo ketadinlogun osu Ikerin (April 17, 2023), won yoo gbadura fun Israeli ni ojo kejidinlogbon osu Ikarun (May 28), awon ogorun milionu wonyi yoo gbadura fun orile-ede Israeli bi won ti se fun Orile-ede China ni ojo kejilelogun osu Ikinni.

Sugbon fun ojo mokanlelogun ti o saaju ojo keji-dinlogbon osu Ikarun, awon alore ti o le ni milionu kan yoo gba awe, won yoo si gbadura pe ki Emi Mimo yo si won lojiji ki o si se ikola fun ogorun milionu awon onigbagbo yi fun ipinnu Re fun Israeli.

Ni kukuru: Darapo mo o le ni milionu kan awon eniyan ti yoo gbadura fun Israeli fun wakati kan (o kereju) lojoojumo – boya iwo nikan tabi eni-meji tabi jubeelo (Matt. 18:20) lori ero-ayelujara, tabi kikorajopo lati gbadura fun Israeli ati lati so fun Emi Mimo lati fowo to okan milionu ogorun kan eniyan ni ojo keji-dinlogbon osu Ikarun (May 28).

**ESE TI A FIN SE APONLE GBI GBADURA FUN JERUSALEMU ATI ISRAELI TO BAYI?**

Ironupiwada orile-ede Israeli (Ise 3:19) ati ijewo pe Jesu ni Mesaya (Matt. 23:39) ni isopo ti o jinle pelu dide Jesu leekeji, Ase Nla naa, ati "iye kuro ninu oku" fun gbogbo ile aye (Romu 11:15). Jesu ki yoo pada wa ayafi igbati awon asaaju ni Jerusalemu ba to jewo pe Oun ni Mesaya gege bi iwe Orin Dafidi 118:26 ti wi (Psalm 118:26).

***Jerusalemu, Jerusalemu…..Eyin ki yoo ri Mi mo (eyi nso nipa ipadabo Jesu) titi eyin o fi wipe, Olubukun li eniti (Jesu) o mbo wa li oruko Oluwa (eyi tumo sipe won ri Jesu bi Mesaya_Psalm 118:26)***
**Matt. 23:37-39**

***19. Nitorina e ronupiwada ki e si tun yipada ki a le pa ese nyin (Israeli) re, ki...***
***20. Ati ki O bale ran Jesu Kristi... 21. Eniti orun ko le saima gba (lati wa li owo otun Baba) titi di igba imupada ohun gbogbo ti Olorun ti so lati enu awon woli re mimo…..(*Acts 3:19-21)**

***Nitori bi titanu won (israeli) baje ilaja aiye, gbigba <u>won (Israeli) yio ha ti ri, bikose iye kuro ninu oku</u>***.*(Ekunrere Ase Nla mbe ninu eyi pelu)* ***Romu 11:15***

A gbagbo pe Awe Agbaye olojo mokanlelogun lati inu Isaiah 62 yi yio yara ru ijo Kristi soke ni akoko yi ni gbogbo orile-ede aye lati le ma jiroro lor iawon ohun ti Bibeli so nipa Israeli. Awe yi yoo pari ni ojo Isinmi Pentikosti ojo keji-dinlogbon osu Ikarun (May 28). Ni ojo yii, awon ogorun milionu onigbagbo yoo gbadura fun Israeli papo ni idahun si ipe Olorun nipase Jason Habbard, Eric Watt ati egbe "110cities" lati ko won jo ni ona yii ni igba merin ni odun 2023.

Wo 110cities.com ni ojo keta-dinlogun osu Ikerin, awon ogorun milionu onigbagbo yi kanna yio gbadura fun gbogbo awon orile-ede ti o wa ni Aringbungbun Ila-Oorun aye.

Gege bi ohun ti awa mo, eyiyoo je igba akoko ninu itan pe egbeerun pupo eniyan yoo fi gbogbo wakati merinlelogun lojumo gbadura nipa awon ileri Olorun fun Israeli fun ojo mokanlelogun. Ohun ti o mu ki ipe si adura yi yato nipe, oun funrarare je okan ninu awon ami akoko ati ti isare akoko ti Olorun ti "***yan fun awon iran ti a o da***" (Psalm 102:13, 18).

***Iwo o… sanu fun Sioni (Jerusalemu); nitori <u>igba</u> ati se oju-rere si i, nitoto <u>akoko na</u> de.***
***Eyi li <u>a o ko fun iran ti mbo</u>, ati awon enia <u>ti a o da</u> yio ma yin Oluwa***
*Psalm. 102:13-18*

Awe olojo mokan-lelogun yii ye "akoko Esiteri kari aye" (Esiteri 4:14-16) ti yoo je isanwo idi-yele fun akoko Esiteri ti yoo keyin kari aye nigbati milionu pupo awon onigbagbo yoo ma gbadura, ti won yoo si ma fi igboya soro lori awon ipinnu Olorun fun Israeli (gege bi ati ri ninu iwe-mimo), won yoo si duro pelu Israeli bi awon alatako Israeli ti nposi titi Jesu yoo fi pada wa. (Sek. 14:1-5). Awe yii tun se pataki lakoko yii bi Israeli se ndojuko opolopo awon ogun nla.

***"Nitori bi iwo ba <u>pa enu re mo patapata</u>*** *(lai dahun)* ***li akoko yi, nigbana ni <u>iranlowo ati igbala awon Ju yio dide lati ibomiran wa.</u> ... tali o si mo bi <u>nitori iru akoko bayi</u> ni iwo se de ijoba?"***
***Nigbana ni Esiteri ran won lo ifi esi yi fun Mordekai pe "Lo pe awon Ju….. jo ki eniyan si ma <u>gbawe fun mi</u>, <u>emi</u> pelu ati awon iranse binrin mi <u>yio gbawe</u> be gege be li <u>emi o si wo ile to oba lo</u>,.. bimo ba segbe mo segbe."*** (Esther 4:14-16)

Mo dupe pupo lowo Tom ati Kate Hess ti won ti dari Ile Adura to wa ni Jerusalemu fun odun merindinlogoji (jhopfan.org) mo tun dupe lowo Rick ati Patricia Ridings ti won ti je adari ni Succat Hallel ni Jerusalemu fun nkan bi ogun odun. (sucathalel.com) ati ile ise iranse adura miran ti won ti da sile ni akoko bi ogun odun ati jubelo sehin.

Ninu awe yi, a gbe titobi Jesu ga, a si gbaju mo akojopo awon ibukun Olorun lori Jerusalemu lati mu Ase Nla na se. A le se pupo si papo ninu Emi Isokan. Johanu 17:21-23.

Gba iwe ofe kan ti akori re je **Moravian Miracle** lati owo Jason Hubbard. Iwe yi so itan iyalenu ti Count Zinzendorf eniti a gbo itan pe o se idasile adura o ni wakati merin-lelogun po mo awon onise iranse igberiko akoko ti ijo Protestant. Wa PDF iwe yii ni Isaiah62fast.com tabi wo itan re lori Youtube pelu akori "Zinzendorf the Rich Young Ruler", tabi wo iforowanilenuwo to dara nipa re lori Remnant Radio.